# Ààyè Ìsinmi Àìsàn àti Ààbò tí a Sanwó Fún: Ohun tí Àwọn Òṣìṣẹ́ Gbọdọ Mọ̀.

Àwọn àtúnse tuntun sí Ofin NYC Ti Àkókò Ti Ó Tọ́ Síni ati Akókò Àìsàn (Òfin Ààyè Ààbò ati Àìsàn Ti A Sanwó Fún) bẹrẹ síí fẹsẹ múlẹ̀ lati Ọgbọn'jọ Osù Kẹsàn-án Ọdún 2020 ati Ọjọ Kini, Osù Kini, Ọdún 2021. Tí o bá nsisẹ́ fún abala àkókò, tabi ẹkunrẹrẹ àkókò nibi isẹ́ kan bí ó ti wù kó se tó, tabi ilé-iṣẹ́ ti kò wà fún èrè ni NYC tàbí tí o bá nṣiṣẹ ninu ilé kan ni NYC gẹgẹ bí oṣiṣẹ abẹ́lé, ka iwé òtitọ yii[1] ki o le ni oye awọn ẹtọ́ òsisẹ. Lábẹ Òfin, àwọn òsisẹ tí ó ní ààbò ni ẹtọ lati lo ààyè isimi ààbò ati àìsàn fún:

- ìlera, pẹlúpẹlù itọjú ara wọn tabi ti mọ̀lẹ́bí kan; Pẹ̀lú
- ààbò, pẹlúpẹlù lati wá iranlọwọ tàbí àwọn igbésẹ ààbò miràn ti osisẹ náà tabi mọlẹbí rẹ lè jẹ́ ẹni ti wọn fiyà jẹ tàbí ti wọn halẹ̀ mọ latari ìwà ipá abẹ́lé tàbí ìfọwọ́pani lára tí o kò fẹ́ fún ìbálòpọ̀, àyọjúràn, tàbí ìfipá tani sókè òkun.

## Àwọn Òṣìṣẹ́ tí Òfin dáàbòbò/Ti Òfin Kò Dáàbòbò

| Tí Ó Dáàbòbò | Tí Kò dáàbòbò |
|---|---|
| • Àwọn òṣìṣẹ́ ni gbogbo àkókò.<br>• Àwọn òṣìṣẹ́ fún àkókò díẹ̀<br>• Àwọn òṣìṣẹ́ abẹ́lé.<br>• Àwọn òṣìṣẹ́ pirogiramu onisẹ isipòpadà.<br>• Àwọn òṣìṣẹ́ tí wọn jẹ mọlẹbí, ṣugbọn tí kìí ṣe onínkan.<br>• Àwọn òṣìṣẹ́ tí kìí gbé ninú Ìlú New York. | • Àwọn akẹ́kọ̀ ní pirogiramu ikẹ́kọ-isẹ́ ijọba àpapọ.<br>• Àwọn òṣìṣẹ́ tí iṣẹ wọn ngba èrè wọn nípa àwọn pirogiramu ẹkọ ọfẹ.<br>• Àwọn òṣìṣẹ́ ẹka ilé iṣẹ ìjọba.<br>• Àwọn olùmuniláradá ti ara, àwọn olùmuniláradá ti ibi isẹ́, àwọn olùmuniláradá ọrọ èdè, àwọn olùgbọ́-ọrọ ti o ni iwe àṣẹ tí Ẹ̀ka Ètò Ẹkọ Ipinlẹ̀ New York (ti wọn bá pè fún isẹ́ àkànṣe nígbà tó bá wù wọn, ṣe ìpinnu nípa ètò ìsẹ́ wọn, ni agbára láti gbà tàbí làti máṣe gbà iṣẹ ti wọn sè ìtọ́ka rẹ̀ sí wọn, ti wọn sì ngba owó wákàtí, ó kéré tán, tí ó jẹ ilọ́po mẹrin owó ọya ìjọba àpapọ̀ tó kéré jùlọ)<br>• Àwọn agbaṣẹ́se aládàáni ti kò kun ojú òṣùwọ̀n itumọ̀ òsìsẹ́ labẹ Ofin Iṣẹ Ṣise ti Ipinlẹ New York.<br>• Àwọn akópa nínú àwọn Pirogiramu Ìrírí Iṣẹ (WEP).<br>• Àwọn òṣìṣẹ́ kan wà l'ábẹ àdéhùn idúnà ádúrà àjùmọṣe. |

*Àkíyèsí:* Ti olùgbanișisẹ rẹ bá ní ètò tí ó fààyè gba awọn òṣìṣẹ́ lati lo ààyè- ìsimi fún ààbò àti àìsàn, ètò náà gbọdọ kún ojú òṣùwọn tàbí ki o kọjá àwọn ohun tí Òfin náà bèère fún.

## Àkíyèsí Àwọn Ẹ̀tọ́ Òṣìṣẹ́

Tí o ba jẹ òṣìṣẹ́ tó wà lábẹ́ ètò yi, olùgbanișisẹ rẹ gbọdọ fún ọ ní ìwé àkọsílẹ̀ Àkíyèsí ẹtọ rẹ sí ààyè isimi ààbò ati àìsàn. O ní ẹ̀tọ́ kan láti gba àkíyèsí náà ní Èdè Gẹ̀ẹ́sì àti ní èdè abínibí rẹ tí ìtumọ kan bá wà ni ojúlé wẹ́ẹ̀bù ti DCWP. **nyc.gov/workers**. **Tọjú ẹ̀dà Àkíyèsí náà tí wọn fún ọ**. Olùgbanișisẹ rẹ gbọdọ fi Àkíyèsí náà sí ibi isẹ ni gbangba nibi ti awọn òṣìṣẹ́ tí le ri.

## Iye Ìgbà Ìsinmi Ààbò àti Àìsàn

| Iye Àwọn Òṣìṣẹ́ Ti Olùgbanișisẹ ti Gbà Ṣiṣẹ | Iye Owó ti ó nwọle fún Olùgbanișisẹ Lọdọọdun. | Iye Ààyè Ìsimi ni Ọdún Kàlẹ́ndà Kọọkan* | Ààyè Ìsimi ti wọn sanwó fún tàbí ti wọn kò sanwó fún |
|---|---|---|---|
| Ẹyọ kan sí Mẹ́rin | Ó din ni Ẹgbẹrun lọnà Ẹgbẹrun Dọ́là Kan | Ó tó ogóji wákàtí | Ti wọn kò sanwó fún |
| | **Bẹrẹ lati Ọjọ Kíni Osù Kini Ọdún 2021.**<br>Ẹgbẹrun lọnà Ẹgbẹrun Dọ́là Kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. | Ó tó ogójì Wákàtí | Ti wọ́n sanwó fún |
| Márùn tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ<br>*tí wọn nșișẹ pẹlú olùgbanișișẹaAládàáni tàbí ti wọn nsisẹ pẹlú olùgbanișisẹ ti kò wà fún jíjẹ èrè*<br>TÀBÍ<br>**Bẹrẹ lati Ọgbọn'jọ́ Osù Kẹsàn-án Ọdún 2020.**<br>Oṣiṣẹ abẹ́lé kan tàbí jù bẹẹ lọ<br>*ti wọn nșișẹ pẹlú olùgbanișisẹ abẹlé.* | Kò yẹ. | Ó tó ogójì wákàtí. | Ti wọ́n sanwó fún |
| **Bẹrẹ lati Ọjọ Kíni Osù Kini Ọdún 2021:**<br>Ọgọrùn tàbí jù bẹẹ lọ<br>*awọn òṣìṣẹ́ tó nșișẹ pẹlú agbanișisẹ aládàáni tabi olùgbanișisẹ tí kò wà fún jíjẹ èrè, tàbí olùgbanișisẹ awọn òṣìṣẹ́ abẹ́lé.* | Kò yẹ. | Ó tó wákàtí mẹ́rindinlọ́gọ́ta | Ti wọ́n sanwó fún |

*Àkíyèsí: "Ọdún Kàlẹ́ndà" túmọ sí àkókò olósù méjìlá kan leralera ti olùgbanișisẹ kan pinnu rẹ̀. Àkíyèsí Àwọn Ẹ̀tọ́ Òṣìṣẹ́ gbọdọ sọ nípa Ọdún Kàlẹ́ndà olùgbanișisẹ náà.

Ti olùgbanișisẹ rẹ bá nilati pèsè ààyè isimi ààbò àti àìsàn pẹlú owó sísan, a gbọdọ sanwó wákàtí wákàtí rẹ fún ọ, ti kò sì gbọdọ din ni owó ọya tó kéré jùlọ nisisiyi.

## Ìgbà Ìsinmi Ààbò àti Àìsàn tí a Kò Lò

Iwọ:

- Bẹrẹ si sàkójọ ààyè Ìsinmi ààbò ati àìlera ní kété ti o bá bẹrẹ isẹ. Sisàkójọ tó kéré jùlọ ni wákàtí kan fún gbogbo wákatí ọgbọ̀n tí o fi șișẹ.
- O le lo ìgbà ìsimi ààbò àti àìsàn ni kété ti o bá ti s'àkójọ rẹ.
- O gbọdọ gbà lati ọdọ olugbanisisẹ rẹ iwe akọsilẹ ni akoko ti o ba ti ngba owó, eyi ti ó sàfihàn iye ààyè isimi ààbò ati àìsàn ti o ti lò, eyi ti o ti sàkójọ, ati èyi ti o ni silẹ.

*Ìyàtọ̀:* Tí o bá wà lábẹ́ àdéhùn ìdúnàá-dúrà àpapọ̀ tó bẹrẹ ní Ọjọ́ Kini, Osù Kẹ̀ẹ̀rin, Ọdún 2014, o ti bẹ̀rẹ̀ láti máa sàkójọ ààyè isimi ààbò ati àìsàn labẹ Òfin bẹrẹ láti déti ti àdéhùn náà dópin.

[1] Kíyèsi déètì tó wà lẹ́hin náà. Ẹ̀ka NYC fún Ìdáàbòbò Olùrajà ati Osisẹ (DCWP) yóò ṣe imúbágbàmu iwé yii bi ó ti yẹ. Tọpinpin nyc.gov/workers fún àwọn imúbágbàmu.

## Àwọn ìdí ti a fi gbà láti lo Ààyè Ìsinmi Ààbò àti Àìlera

O le lo ààyè ìsinmi ààbò àti àìlera láti gba ìsinmi níbi iṣẹ́ nígbàtí:

- O ní àìsàn, ìpalára, tàbí ipò àìlera ọpọlọ tàbí ti ara; o ní láti ṣe àyẹ̀wò ìlera, ìtọ́jú, tàbi ìtọ́jú àìsàn ọpọlọ tàbí ti ara rẹ, ìpalára, tàbí ipò; o ní láti gba ìtọ́jú ara tí ńdènà àìsàn.
- O gbọ́dọ̀ tọ́jú mọ̀lẹ́bí kan tó nílò àyẹ̀wò ìtọ́jú ara, ìtọ́jú ìlera, tàbí tó nílò ìtọ́jú ara tàbí àìsàn ọpọlọ, ìpála, tàbí ipò ìlera, tàbí ẹni tó nílò ìtọ́jú tí ńdènà aìsàn.
- Okòwò agbanisíṣẹ́ rẹ dópin nítorí pàjáwìrì ìlera gbogbogbò tàbí o ní láti tọ́jú ọmọ kan èyítí ilé-ìwé rẹ̀ tàbí olùpèsè ìtọ́jú rẹ̀ kò ṣiṣẹ́ nítorí pàjáwìrì ìlera gbogbogbò.
- Ìwọ tàbí mọ̀lẹ́bí kan le ní ìrírí ìwà ipá abẹ́lé ti ìhàlẹ̀ tàbí ìṣe tàbí ìfọwọ́pa lára ti ìbálòpọ̀, àyọjúràn, tàbí fífí ipá mú ni lọ òkè òkun, o sì ní láti gbé ìgbésẹ̀ tó ṣe pàtàkì láti mupadàbọsipò ààbò ati ìlera ọrọ́-ajé tàbí ààbò rẹ tàbí ti àwọn mọ̀lẹ́bí rẹ tàbí láti dá ààbò bo awọn ọrẹ rẹ tàbí awọn tí ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú rẹ, pẹ̀lúpẹ̀lù:
    - Gba àwọn ìtọ́jú láti ilé ààbo kúrò ninu ìwà ipá abẹ́le, ibudó awọn oni wàhálà ìwà fífi ipá báni lòpọ̀, tàbí ètò àwọn iṣẹ́ míràn.
    - Kópa nínú ètò ààbò, isilọ síbò míràn, tàbí gbé àwọn ìgbésẹ̀ míràn láti tọ́jú ààbò rẹ tàbí ti mọ̀lẹ́bí rẹ, pẹ̀lú fífí orúkọ ọmọ sílẹ̀ ní ilé-ìwé titun kan.
    - Bá agbẹjọ́rò kan tàbi olùpèsè iṣẹ́ ìgbàlódé pàdé láti gba àlàyé àti ìmọ̀ràn tó jọ mọ́ gbígba ọmọ sọ̀dọ́; àbẹ̀wò; àwọn ìṣòro ìgbéyàwó; àwọn àṣẹ ààbo; ọ̀rọ̀ ìrìn-àjò; ilé gbígbé; ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní ibi iṣẹ́; ilé gbígbé tàbí kirẹditi oníbàárà.
    - Jábọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ abẹ́lé kan pẹ̀lú àgbófinró tàbí ṣe ìpàdé pẹ̀lú ilé-iṣẹ́ agbẹjọ́rò ti agbègbè kan.

Òfin náà fọwọ si àwọn ènìyan wọ̀nyí bíi "àwọn mọ̀lẹ́bí:"

- Ẹnikẹ́ni tí ìṣepọ̀ rẹ̀ pẹ̀lú agbanisíṣẹ́ bá dàbí ti ẹbí
- Ọmọ (tí a bí, tí a gbàtọ́, tàbí tí a fi ṣe ọmọ; olùtọ́jú tó bá òfin mu; ọmọ agbanisíṣẹ́ tí ń dúró *bíi òbí*)
- Ọmọ-ọmọ
- Ọkọ tàbí aya
- Alájọṣe Abẹ́lé
- Òbí
- Òbí àgbà
- Ọmọ tàbí Òbí ọkọ tàbí aya òṣìṣẹ́ tàbí alájọṣe abẹ́lé
- Ọmọ ìyá (pẹ̀lú ìbátan, àgbàtọ́, tàbí ti ìyá míràn)
- Ẹlòmíràn tó bá òṣìṣẹ́ tan nípasẹ̀ ẹ̀jẹ̀

## Àkíyèsí Ṣáájú Àkókò

Tí a bá ti rò àìní náà tẹ́lẹ̀, agbanisíṣẹ́ rẹ le nílò àkíyèsí ìṣáájú tí ó tó ọjọ́ méjè ti èrò rẹ láti lo ààyè ìsinmi ààbò àti àìsàn. Tí a kò bá ro àìní náà tẹ́lẹ̀, agbanisíṣẹ́ rẹ le nílò kí o fún òun ní àkíyèsí ní kété tó bá ti ṣeéṣe. Agbanisisẹ rẹ le fẹ ki o pèsè àkọsilẹ ijẹrisi wipe o lo ààyè isimi ààbò tabi àìsàn fun awọn ohun ti ó nii se pẹlù ààbò tabi àìsàn.

## Àkọsílẹ̀

Agbanisíṣẹ́ rẹ le nílò àkọsílẹ̀ tí ó jojú fun idaniloju ti o bá lò ju ọjọ́ isẹ méta lọ leralera gẹgẹ bi ààyè isimi ààbò tabi àìsàn. Agbanisisẹ rẹ le nilò:

- ìwé pélébé kan ti olùpèsè ìtọ́jú ilera ti a fún lásẹ buwọlù fún ààyè isimi àìsàn; tàbi
- àkọsilẹ lati ọdọ olupèsè isẹ ilú, olùpèsè isẹ ofin, ọkan lara awọn àlùfáà, tàbi lẹta ti o kọ pẹlu ifọwọsi amòfin ti ó sàfihàn idi ti o fi nilò isimi ààbò.

Olugbanisisẹ rẹ le máse bèèrè àkọsilẹ yẹn, sàlàyé idi ti o fi lo ààyè isimi ààbò tabi àìsàn. *Àwọn òfin miran le bèrè àfihàn.*

Agbanisiṣẹ rẹ gbọdọ sanwó pada fún ọ fun:

- Awọn owó ti awọn olupèsè ìtọ́jú ilera bù fún ọ lati san láti pèsè akọsilẹ ààyè isimi àìsàn; ati
- gbogbo owó tí ó jọjú ti o ná lati gba akọsile ààyè isimi ààbò.

## Ààyè Ìsinmi Ààbò àti Àìsàn tí a Kò Lò

O lè sún èyí tí ó tó wákàtí ogójì (tabi, ti ó bá yẹ, wákàtí mẹrindinlọgọta bẹrẹ lati Ọjọ Kini Osù Kini, Ọdún 2021) ti ààyè ìsinmi ààbò àti àìsàn tí a kò lò ni o le sún sí ọdún Kàlẹ̀ndà tí ń bọ̀. Ṣùgbọ́n, agbanisíṣẹ́ rẹ ní láti gbà ọ́ lááyè láti lo wákàtí tí ó tó ogójì (tàbí mẹrindinlọgọta) ti ààyè ìsinmi ààbò àti àìsàn láàrín ọdún kalẹ̀nda kan.

## Ìgbẹ̀san

Agbanisíṣẹ́ rẹ kò le gbẹ̀san lára rẹ fún bibèèrè fún tabi fún lilo ààyè isimi ààbò ati àìsàn. Gbigbẹsan pẹ̀lú èyíkéyìí ninú ìhàlẹ̀, ìbániwí, ìgbaṣẹ́ lọ́wọ́ ẹni, ìrẹsilẹ nipò isẹ, ìdádúró díẹ̀, tàbí ìdínkù nínú wákàtí iṣẹ́ rẹ, tàbí èyíkéyií ti i sèlòdì si ọ lẹ́nu iṣẹ́, nitori pé o sàmúlò tabi o gbiyanjú lati sàmulò ẹ̀tọ́ rẹ lábẹ́ Òfin náà, eyi ti ó pẹlu awọn igbèsẹ tó nii se pẹlú ipò isilọ si ìlu miràn tabi àsẹ lati sisẹ.

## Awọn Awuyẹwuyẹ

O le kọwé awuyẹwuyẹ si DCWP. Láti gba fọ́ọ̀mù awuyẹwuyẹ, lọ sí [nyc.gov/workers](nyc.gov/workers) tàbí kí o kàn sí 311 (212-NEW-YORK ìta NYC).

*A ṣe imúbágbàmu ni rẹ̀ ní Ogún'jọ, Osù Kọkànlá, Ọdún 2020.*